**Àwọn àìdọ́gba ọrọ̀-ajé tó wà láàárín àwọn obìnrin àti ọkùnrin**
Ọmọrìnmọlá Akínwándé

Ní gbogbo agbayé, àwọn àìdọ́gba ọrọ̀-ajé wà láàárín ènìyàn nítorí pé wọ́n jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. Àbá jade ètò ìwádìí tí UN Women fi yé wa pé ní àgbáyé, àwọn ọkùnrin gbá 23% jù àwọn obìnrin ní owó níbi-iṣẹ́[1]. UN Women náà wì pé àwọn obìnrin máa ń ri ìdíwọ̀ nínú ojà-iṣẹ́. Èyí jẹ́ nítorí pé kò sí ìdọ́gba nínú ẹ̀kọ́, ìlera àti òwò fún obìnrin. Pẹ̀lúpẹ̀lú, nínú àwọn orílẹ̀-èdè onírúurú, wọ́n ń fi ààlà lórí àwọn obìnrin tí wọ́n ipò olórí lẹnú iṣẹ́. Wọ́n gbérò nǹkan tí obìnrin àti ọkùnrin lè ṣe láwùjọ[2]. Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ èèyàn ni ìtumọ̀ wọ́n lórí àwọn àìdọ́gba ọrọ̀-ajé tó wà láàárín àwọn obìnrin àti ọkùnrin.  Àwọn lè sọ pé àìdọ́gba nínú owó oṣù láàárín ọkùnrin àti obìnrin kò sí mọ́, paapaa jù lọ nínú ètò ọrọ̀-ajé tí Òkè-Ókun, níbi tí àwọn obìnrin àti ọkùnrin ni àǹfààní ọrọ̀-ajé tó dọ́gba. Bẹ̀ẹ̀ ni, àwọn miíràn rò pé àìdọ́gba yìí lágbára tò bẹ̀ẹ̀gẹ̀, ó maa tó ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ọdún kì ìtúnṣe tò lè wáyé[3].

Ní bíi ọgọ́rùn-ún ọdún lẹ́yìn, àwọn obìnrin ni àǹfààní jù láti siṣẹ́ tì o ń sanwó nínú àwọn orílẹ̀-èdè tí Ìgbimọ fún Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ àti Ìlọsókè Ọrọ̀-Ajé (Organisation for Economic Co-operation and Development - OECD) àti orílẹ̀-èdè mìíràn bíi Russia àti Japan. Nígbà yìí, àìdọ́gba owó oṣù láàárín àwọn ọkùnrin àti obìnrin lọ́ọ́lẹ̀. Fún apẹẹrẹ, lọ́dún 1970, àìdọ́gba owó oṣù láàárín àwọn ọkùnrin àti obìnrin ni Ìlú Ọba (UK) jẹ́ 50%, ṣùgbọ́n ní ọdún 2016 àìdọ́gba wa sìlẹ̀ di 17%. Ní àyíká àgbáyé, àwọn orílẹ̀-èdè tí tẹ̀síwájú láti fún àwọn obìnrin ní àwọn ẹ̀tọ́ láti nilẹ̀. Ní ọdún 1970, àwọn orílẹ̀-èdè tó le ni ààdọ́ta fi ààlà lórí àwọn obìnrin láti ni, rà àti tà ilẹ̀. Ààdóta ọ́dún léyìn ìgbà náà ní ọdún 2016, àwọn orílẹ̀-èdè mẹ́rìnla lásán ni wọ́n fi ààlà lórí obìnrin[4].

Bẹ̀ẹ̀ náà, àwọn obìnrin ń rí ààlà púpọ̀ nígbà tí wọ́n fẹ́ wọnú ọ̀jà-isé. Àwọn ààlà yìí lágbara jù lọ nínú orílẹ̀-ède tó wà ní Persian Gulf àti Àríwá Afíríkà. Àwọn ìṣirò fi hàn pé àwọn ọkùnrin ṣiṣẹ́ jù àwọn obìnrin nínú ọ̀jà-iṣẹ́ ni ìdàkan nínú mẹ́rìn (25%). Ilé-iṣẹ́ Ọjà-Iṣẹ́ Gbogbo Àgbáyé (International Labour Organization - ILO) ni pé ìgbéyàwó ń fa ìdíwọ̀ lóri àwọn obìnrin tó fẹ́ siṣẹ́ tó máa sanwó. Ní àwọn orílẹ̀-èdè tó lọ́rọ̀, kò wọ́pọ̀ kì obìnrin tó ni ọkọ wá iṣẹ́ tó sanwó. Àwọn obìnrin tó ń ṣiṣẹ́ ilé bíi oúnjẹ síse jù àwọn ọkùnrin lọ. Eléyìí jẹ́ ìdíwó fún àwọn obìnrin láti wọ ọ̀jà-iṣẹ́. Àwọn obìnrin tun ń rì àwọn ìṣòro nítorí pé kò sí ètò ọkọ̀ ìjọba, ìtọ́jú fún ọmọdé àti àwọn ogbó wọn. Ní ọdún 2016, ìwé ìbéèrè ILO-Gallup sọ pé 20% nínú àwọn ọkùnrin àti 14% nínú àwọn obìnrin gbérò pé àwọn obìnrin kò gbọdọ̀ nísẹ́ tó sanwó[5].

Ìwádìí láti LinkedIn, sọ pé àwọn obìnrin jẹ́ 42% nínú oṣiṣẹ́ àgbáyé. Àtipé, ILO ròyìn pé àwọn obìnrin wà jẹ́ 40% oṣiṣẹ́ àgbáyé ní ọdún 2021. Ní ẹ̀ka ìwòsàn, àwọn obìnrin pọ̀; wọ́n jẹ́ 65% nínú

---

1 "Equal pay for work of equal value | UN Women – Headquarters." https://www.unwomen.org/en/news/in-focus/csw61/equal-pay. Accessed 11 Dec. 2023
2 "Gender inequality persists in the world of culture, underlines a new ...." 22 Oct. 2014, https://www.unesco.org/en/articles/gender-inequality-persists-world-culture-underlines-new-report. Accessed 11 Dec. 2023.
3 "Women and Girls – Closing the Gender Gap | United Nations." https://www.un.org/en/un75/women_girls_closing_gender_gap. Accessed 11 Dec. 2023.
4 "Economic Inequality by Gender - Our World in Data." https://ourworldindata.org/economic-inequality-by-gender. Accessed 23 Dec. 2023.
5 "The gender gap in employment: What's holding women back? - ILO." https://www.ilo.org/infostories/en-GB/Stories/Employment/barriers-women. Accessed 23 Dec. 2023.

àwọn oṣiṣẹ́. Ṣùgbọ́n, kò sí obìnrin púpọ̀ ni àwọn ẹ̀ka onísẹ́ epo rọ̀bì, ìṣúra wíwá (wọ́n jẹ́ 22.7%) àti ẹ̀ka oun amáyédẹrùn (wọ́n jẹ́ 22.3%). Àwọn ìṣirò láti LinkedIn náà sọ pé àìdọ́gba ńlá wà láàárín àwọn ọkùnrin àti obìnrin nínú àwọn tó jẹ ipò olórí nibiṣẹ́. Nínú gbogbo àwọn tó ń jẹ́ olórí níbiṣẹ̀ ní gbogbo àgbáyé, àwọn obìnrin ń jẹ́ 32%. Ní ọdún 2016, oye obìnrin tí o dé ipò olórí gá jù ti àtèyìnwá lọ. Fún apẹẹrẹ, nínú ìmọ̀ ẹ̀rọ, iṣẹ́ ìbánisọ̀rọ̀ àti iṣẹ́ ìjọba, àwọn obìnrin ń pọ̀ síi nípa ìpìnméjì nínú ọgọ́rùn-ún[6].

Bíi a tí kọ tẹ́lẹ̀, àwọn orisirisi àṣà ní ohun ń fa ààlà lórí àwọn obìnrin. Fún apẹẹrẹ, ní orílẹ̀-èdè Vietnam, àwọn èèyàn gberò pé àwọn ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ìjìnlẹ̀, ìṣirò àti ìmọ̀ ẹ̀rọ (tàbí àwọn ẹ̀kọ́ STEM) ṣòro fún àwọn ọmọbìnrin. Nítorí náà, àwọn ọmọkùnrin ń kọ ẹ̀kọ́ STEM jù lo. Wọ́n gbẹ́sẹ̀ lé àwọn obìnrin láti ṣe nínú iṣẹ́-ámódàjù mẹ́tàdínláàádọ́rin (70)[7]. Ní Uzbekistan, áwòn ènìyàn tó dáhùn sì ìwé ìbéèrè láti United Nations Development Programme (UNDP) fi hàn pé ìmọ̀ ẹ̀rọ àti ìmọ̀ égbògí dá fún omọkùnrin, nígbàtí ẹ̀kọ́ iṣẹ́ ìlera ati iṣẹ́ olùkó dá fún obìnrin. Bẹ́ẹ̀ náà, àwọn èèyàn gberó pé àwọn obìnrin gbọdọ̀ wà pẹ̀lú ẹbí àti ọmọ wọn, kí ọkùnrin gbọdọ̀ jẹ́ olórí. Nitorì èyí, àwọn obìnrin jẹ́ 38% lásán nínú àwọn olókòwò ni ìlú Uzbekistan[8].

Ní àkámá, àwọn kan ń gberò pé kò si áìdọ́gba nínú àwọn orílẹ̀-èdè tó gbésẹ̀ lé ìyàṣọ́tọ̀ owó oṣù láàárín àwọn ọkùnrin àti obìnrin. Àwọn obìnrin ni iṣẹ́ tó pa owò kéré jù àwọn ọkùnrin lọ. Ní Amẹ́ríkà, àwọn obìnrin jẹ́ ìpín méjì nínú mẹ́tà tí wòn siṣẹ́ tí kò san jù $30,000 lọ́dún àti ìpín kan nínú meta ni awọ́n tí wòn siṣẹ́ tó sanwo jù $100,000 lọ́dún[9]. Ní Ìlú Ọba (UK), níbi ti wón ti gbẹ́sẹ̀ lé ìyàṣọ́tọ̀ owó-ise lọ́dún 1970 àti 2010, 99% nínú àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ àti onímọ̀ ọkọ̀ jẹ́ ọkùnrin, ṣùgbọ́n 98% ninu àwọn olùkọ́ ilé-ìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀ jẹ́ obìnrin. Àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ àti onímọ̀ ọkọ̀ ṣiṣẹ́ fún wákàtí 49, nìgbàtí àwọn olùkọ́ ilé-ìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀ ṣiṣẹ́ fún wákàtí 31. Àwọn onímọ̀ ẹ̀rọ àti onímọ̀ ọkọ̀ ń gbá £10,428 lọdún jù[10] àwọn olùkọ́ onìwé alákọ́bẹ̀rẹ̀[11].

Àìdọ́gba láàárín àwọn obìnrin àti ọkùnrin paapaa nípa ọrọ̀-ajé o ń ṣì n ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́. Àwọn ìwádìí tí fi hàn pé ọ̀rọ̀ yìí ṣe pàtàkì gan. Iṣẹ́ sì pọ̀ tí a ni láti ṣe kí a lè dojú àìdọ́gba bolè.

6 "Global Gender Gap Report 2023 - The World Economic Forum." 20 Jun. 2023, https://www.weforum.org/publications/global-gender-gap-report-2023/in-full/gender-gaps-in-the-workforce/

7 "Vietnam: Breaking gender stereotypes that hinder women's ...." 20 Oct. 2015, https://blogs.worldbank.org/eastasiapacific/vietnam-breaking-gender-stereotypes-hinder-women-s-empowerment. Accessed 27 Dec. 2023.

8 "Negative Impact of Gender Stereotypes and Patriarchal Attitudes on ...." https://www.undp.org/sites/g/files/zskgke326/files/2023-03/Gender%20Stereotypes%20final%20%284%29.pdf. Accessed 27 Dec. 2023.

9 "5 Fast Facts: The Gender Wage Gap | U.S. Department of Labor Blog." 14 Mar. 2023, http://blog.dol.gov/2023/03/14/5-fast-facts-the-gender-wage-gap. Accessed 23 Dec. 2023.

10 "Vehicle technicians, mechanics and electricians - Career Smart." https://careersmart.org.uk/occupations/vehicle-technicians-mechanics-and-electricians. Accessed 23 Dec. 2023.

11 "Nursery nurses and assistants - Careersmart." https://careersmart.org.uk/occupations/nursery-nurses-and-assistants. Accessed 23 Dec. 2023.